Ìrìnkèrindò nínú

# Sáyẹ́ǹsì Onímọ̀-Ohun-Àtijọ́



Ìwé yìí jẹ́ ti:

______________________________

Orúkọ

Ẹkọ́ ìmọ̀ sáyẹ́ǹsì fún Onímọ̀-Ohun-Àtijọ́ lọ́jọ́ iwájú





Ìwé Akọ́niláwọ̀ láti ọwọ́

Ilé Ẹkọ́ Max Planck fún Ìmọ̀ Sáyẹ́ǹsì Nípa Ìtàn Ẹdá

## Ìrìnkèrindò nínú

# Sáyẹ̀nsì Onímọ̀-Ohun-Àtijọ́






Ìwé yìí jẹ́ ti:

______________________________

Orúkọ

Ẹ̀kọ́ ìmọ̀ sáyẹ̀nsì fún Onímọ̀-Ohun-Àtijọ́ lọ́jọ́ iwájú

**Ìwé Akọ́niláwọ̀ láti ọwọ́**

**Ilé Ẹ̀kọ́ Max Planck fún Ìmọ̀ Sáyẹ̀nsì Nípa Ìtàn Ẹ̀dá**

**Ilé-işẹ́ Ìtẹ̀wé:** Ilé Ẹ̀kọ́ Max Planck fún Ìmọ̀ Sáyẹ́ǹsì Nípa Ìtàn Ẹ̀dá
**Olóòtú:** Christina Warinner
Amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ Olóòtú: Jessica Hendy
**Àwọn Òǹkọ̀wé:**
Zandra Fagernäs
Jessica Hendy
Allison Mann
Åshild Vågene
Ke Wang
Christina Warinner

**A túmọ̀ Iṣẹ́ yìí sí èdè Yorùbá láti ọwọ́:**
Orúkọ Ògbufọ̀: Onímọ̀ ìṣègùn Òyìnbó Ìféolúwa Òjélabí. Olùkàwé: Ìyáàfin Rachael F. Àkàndé.

A ṣe àgbékalẹ̀ ìwé Akọ́niláwọ̀ yìí gẹ́gẹ́ bi abala àlàkalẹ̀ ẹ̀kọ́ nínú ìmọ̀ Sáyẹ́ǹsì Aṣàfihàn Àwòrán.

Attribution-NonCommercial-ShareAlike
CC BY-NC-SA

DOI: 10.17617/2.3561781
2024




# Ẹni Tí A Jẹ́

Àwọn onímọ̀ sáyẹ́nsì Aṣèwádìí-Ohun-Àtijọ́ jẹ́ àwọn Olùwádìí tó ń ṣàmúlò ìlànà ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ sáyẹ́nsì àti ọ̀nà ìṣèwádìí tó múnádóko láti ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ìbéèrè nípa ènìyàn ìsaáju tó ti kọjá lọ. Àwọn ohun tí ó ṣẹlẹ̀ ṣẹ́yìn nípa ìtàn Ìràn àwọn ẹ̀dá àti ènìyàn àtijọ́.

## Nínú Ilé Ifimọ̀ Sáyẹ́nsì Ṣe Ìwádìí...


Nígbà tí a bá ń ṣàyẹ̀wò àbúdà àjogúnbá (DNA) ìràn ènìyàn àtijọ́, Àwọn onímọ̀ sáyẹ́nsì gbọ́dọ̀ máa ṣiṣẹ́ nínú àwọn yàrá tó mọ́ tónítóní, kí wọ́n sì wọ ẹ̀wù, ìbọ̀wọ́, àti bàtà láti dáàbò bo àwọn èròjà tí a kójọ fún àyẹ̀wò kúrò lọ́wọ́ ìdíbàjẹ́ àbúdà àjogúnbá ìràn ènìyàn òde-òní. Àwọn onímọ̀ ìjìnlẹ̀ sáyẹ́nsì máa ń lo oríṣríṣi ẹ̀rọ àti irin-iṣẹ́ láti ṣe ìwádìí nípa àwọn nǹkan àtijọ́.





## Ní Oko Ìwádìí...

Àwọn onímọ̀ ìjìnlẹ̀ sáyẹ́nsì máa ṣiṣẹ́ pẹ́kípẹ́kí pẹ̀lú àwọn Aṣèwádìí-nǹkan-Àtijọ́ láti wú jáde àti láti ṣe àkójọpọ̀ nǹkan àtijọ́ fún àyẹ̀wò ní ilé ìṣèwádìí sáyẹ́nsì. Èyí le níí ṣe pẹ̀lú àwọn nǹkan tí ó wà ní ibojì òkú, ṣíṣe àkójọpọ̀ àwọn ìkòkò àtijọ́ yòókù, ṣíṣe ìdánimọ̀ àwọn egungun ẹranko àtijọ́ nínú igbó (kòtò àtìtàn), tàbí ìṣíkúrò àwọn gẹ̀dẹ̀gẹ́dẹ̀ ewéko àtijọ́.


Ìwújáde àwọn nǹkan àtijọ́ ni oko ìwádìí
Àwọn Onímọ̀ Sáyẹ́ǹsì Aṣèwádìí-Ohun-Àtijọ́ máa ń rin ìrìn-àjò káàkiri ayé láti máa ṣe ìwádìí nípa ìtàn ìran ènìyàn àti ohun tí ó ṣaájú ìtàn ìran ènìyàn. Ní àfikún, láti le wú ohun Àdáyébá jáde láti inú ihò, àwọn agbègbè kan wà tó nílò ìṣàmúlò àwọn irinsẹ́ pàtàkì. Fún àpẹẹrẹ, láti gun àwọn orí òkè Himalaya, Aṣèwádìí-Ohun-Àtijọ́ gbọ́dọ̀ gba ìwé àṣẹ láti rìn, bákan náà ni ó gbọ́dọ̀ ṣàmúlò àwọn irinṣẹ́ fún òkè gígùn.
NATIONAL TRUST FOR NATURE CONSERVATION
Entry Permit
(ACA/MCA/GCA)
Receipt No. 0281630
Entry Permit No.
Full Name:
Date of Birth:
Passport No.
Nationality:
Purpose of Visit :
Entry Permit Issuing Authority
Signature
Full Name:
Designation:
Date:
NATIONAL TRUST FOR NATURE CONSERVATION
Entry Fee Receipt
Ticket No
Date
Nationality
Authorized Signatory
TOURIST COPY
TREKK
gration Officer



Ìlú Samdzong,
ní ilẹ̀ Nepal

## Ìdọ̀tí Eyín

Èyí ni a tún mọ̀ sí ìpẹ́ ara eyín, Ìdọ̀tí eyín jẹ́ ẹ̀yà ara rẹ kan soso tí o máa ń dì bí òkúta nígbà tí o wà láàyè. Níbẹ̀ ni oúnjẹ àti kòkòrò àìfojúrí bakitéríà máa ń sá pamọ́ sí, a sì máa ń lò láti ṣe ìwádìí ipò ìlera ènìyàn àtijọ́ àti oúnjẹ àtijọ́.

## Egungun àti Eyín

Àwọn egungun àti eyín ní àwọn èérún àbùdá àjogúnbá (DNA) èyí tí a le lò láti tọ ipasẹ̀ ìrìnkèrindò àwọn ènìyàn àtijọ́ àti láti ṣàfihàn àwọn àbùdá ara wọn bíi irun orí, ojú, àwọ̀, pẹ̀lú àbùdá àjogúnbá tí ó níí ṣe pẹ̀lú ibùgbé wọn. Eyín àwọn ènìyàn tí ó kú nígbà àjàkálẹ̀ àrùn náà le ní àbùdá àjogúnba ti kòkòrò àrùn tó ṣe wọ́n.






## Egungun Ẹranko

Àwọn egungun ẹranko le kọ́ wa nípa oúnjẹ àti ètò ọrọ̀-ajé tí àwọn àwùjọ àdáyébá. Wọ́n sì tún wúlò fún bí a ṣe lè mọ ọjọ orí tàbí iye ọdún tí àwọn èròjà yìí ti lò láyé àti láti ṣe àgbéyẹ̀wò àti àtúnṣe àwọn àyíka àtijọ́.

## Ìkòkò Àtijọ́ Yòókù

Èépá oúnjẹ àti ìyókù ìkòkò àtijọ́ le ní èròjà amáradàgbà láti ara ewéko tàbí ẹranko, àwọn èérún igi àìfojúrí, àti ìṣàwárí àwọn ọ̀rá-ẹran tàbí epo tí a ti fi ṣe oúnjẹ. Fífi ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ ṣe ìwádìí lára ìkòkò àtijọ́ lè kọ́ wa nípa oúnjẹ àtijọ́ àti ọ̀nà tí àwọn ènìyàn àtijọ́ máa ń gbà pèsè oúnjẹ wọn látijọ́.

# Ohun Tí A Ń Ṣe Ìwádìí Nípa Rẹ̀

Àwọn Onímọ̀ Sáyẹ́nsì Aṣèwádìí-Ohun-Àtijọ́ máa ń lo ìlànà ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ sáyẹ́nsì àti àwọn ìmọ̀-ẹ̀rọ tó múnádóko láti ṣe ìwádìí àti láti ṣàgbéyẹ̀wò ìbéèrè nípa ohun tó ti ṣẹlẹ̀ sí ènìyàn látẹ̀yìnwá. Nípa lílo àwọn irinṣẹ́ tó tọ̀nà, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìmọ̀ ni a le ní láti ara ohun kékeré kan tí a ṣe ìwádìí lé lórí, àwọn nǹkan bíi egungun kan, eyín kan tàbí ìkòkò kan.

# Ǹjẹ́ o mọ̀ pé?

Oríṣi àwọn ènìyàn kan tí ìrísí wọn jọ ti ìnàkí (ṣènìyàn-ṣẹranko) ti parun kúrò láyé láti nǹkan bíi ẹgbẹ̀rún lọ́nà ogójì ọdún sẹ́yìn, ṣùgbọ́n àbùdá àjogúnbá àwọn ènìyàn yìí sì wà nínú ẹ̀jẹ̀ púpọ̀ nínú àwọn ènìyàn tí kìí ṣe ara ilẹ̀ Afíríkà.



# Orírun Ènìyàn

Àbùdá àjogúnbá (DNA) nínú ẹ̀jẹ̀ ń ràn wá lọ́wọ́ láti ní òye nípa àyipadà tí o dé bá àwọn ẹ̀dá tí ó súnmọ́ ènìyàn jùlọ: Àwọn ènìyàn bí ìnàkí (ṣènìyàn-ṣẹranko).





## Idàgbàsókè Ẹ̀dá

Nípa ṣíṣẹ àgbéyẹ̀wò eyín àti egungun àwọn ènìyàn àtijọ́, a le ṣe àwári ìgbé-ayé àwọn Baba-ńlá wa àti bí àwa ènìyàn ṣe wá da irú ẹ̀dá tí a jẹ́ lónìí.

# Ìgbòkègbodò Àtijọ́

Àbùdá àjogúnbá (DNA) atijọ́ èyí tí a rí gbà láti ara eyín àti àwọn egungun ni a le lò láti ṣe àwárí àti àtúnṣe ìtàn tó ṣaájú ìmọ̀ mọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà nípa ìṣípò-padà àwọn ènìyàn àtijọ́ láti ibi kan lọ sí ibòmíràn.

Àwọn ènìyàn ilẹ̀ Síkítíà, ní àárín gbùngbùn Ésíà
Ìgbà ìṣàmúlò irin, 700BC




## Ǹjẹ́ o mọ̀ pé?

Irinṣẹ́ tí a fi ń ka ọjọ́-orí tàbí iye ọdún àwọn ohun àtijọ́ tí a ń pè ní Rẹdiokábọ́ọ̀nù tàbí 14C jẹ́ èròjà ẹ̀yà áísótóòpù tí kò dúro sójú kan, èyí tí àwọn ewéko máa ń gbà láti ara afẹ́fẹ́, ní àkókò tí wọn bá ń jẹun nípa ìrànlọ́wọ́ oòrùn. (photosynthesis). Àwọn ẹranko máa ń gba àbùdá ìtànsán-afẹ́fẹ́ Rẹdiokábọ́ọ̀nù sínú ẹran ara wọn nígbà tí wọn bá jẹ ewéko. Rẹdiokábọ́ọ̀nù máa ń jẹrà nígbà tí ó bá yá. Nípa ṣíṣe òdiwọ̀n iye àbùdá ìtànsán-afẹ́fẹ́ Rẹdiokábọ́ọ̀nù (14C) nínú àwọn nǹkan àtijọ́, ó ṣe é ṣe láti ṣàwárí iye ọdún tí ẹ̀dá kan ti wà láàyè.


## Ìlànà Ìsòdiwọ̀n Ìtànsán-Afẹ́fẹ́ Nípa Rẹdiokábọ́ọ̀nù


Ìsòdiwọ̀n Àbùdá Ìtànsán-Afẹ́fẹ́ Rẹdiokábọ́ọ̀nù jẹ́ ìlànà kan tí a le lò láti ṣàwárí ọjọ́-orí àwọn ènìyàn àtijọ́, àwọn ẹranko àti àwọn ewéko títí di bíi ọjọ́-orí tó tó ẹgbẹ̀rún-lọ́nà-ogójì ọdún.

# Àwọn Oúnjẹ Àtijọ́

Àwọn onímọ̀ sáyẹ́ǹsì le ṣàmúlò Ẹ̀rọ-Asàfihàn-Kòkòrò-Àìfojúri (máíkírósíkóòpù) láti ṣàwárí àwọn èérún oúnjẹ tó wà lára àwọn ìkòkò àtijọ́ àti lára eyín ènìyàn àtijọ́. Ìṣàwárí "àwọn èérún oúnjẹ àìfojúrí yìí" (microfossil) ti kọ́ wa nípa àwọn oúnjẹ àtijọ́ tí àwọn ènìyàn ilẹ̀ Máyà, ti agbegbè Mẹ́soamẹ́ríkà jẹ ní àkókò to ti ju ẹgbẹ̀wá ọdún sẹ́yìn.



# Sísọ Ẹranko Di Ẹran Ilé/ Ẹran Ọ̀sìn

Láti nǹkan bíi ẹgbẹ̀rún mẹ́wàá ọdún (10,000) sẹ́yìn ni àwọn ènìyàn ti ń ṣe àṣàyàn láti má ṣe ìtọ́jú àwọn ewéko àti ẹranko nítorí àwọn àbùdá kan ní pàtó. Ẹran-ọ̀sìn (ẹrinlá) jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ẹranko àfisohúnjẹ tí a sọ di ẹran ilé, àwọn ènìyàn àtijọ́ sì máa ń lò wọ́n fún ìsúnkì, ẹran jíjẹ, wàrà (mílîkì), àti àwọ lóríṣiríṣi.

## Ǹjẹ́ o mọ̀ pé?


A sọ ẹrinlá (ẹran-ọ̀sìn) di ẹran ilé láti àra ẹranko áúroṣì (aurochs), ẹranko búburú bófîìdì (bovid) tí kò sí láyé mọ́ báyìí. Ẹrí ìṣaájú nípa sísọ ẹranko di ẹran-ọ̀sìn wá láti agbègbè Anatónía Pẹ̀nísulà, ni ibi ti a ń pè ní orílẹ̀-èdè Tọ́kì báyìí.









## Orírun Ibi Ìfúnwàrà


A kò le sọ pàtó nípa ibi tí a ti kọ́kọ́ fún wàrà lágbàáyé, ṣùgbọ́n àwọn onímọ̀ ìjìnlẹ̀ sáyẹ́ǹsì Aṣèwádìí-ohun-àdáyébá lo irinṣé aṣèpínyà-èròjà (mass spectrometry) láti ṣàwárí èròjà amáradàgbà tí ó wà lórí eyín àwọn ènìyàn àtijọ́, nípa bẹ́ẹ̀ ni wọ́n ṣe ṣe àwárí ìtàn àtijọ́ nípa ibi ìfúnwàrà.















## Mọngolíâ (Ilẹ Koríko)

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àti oríṣiríṣi ẹranko ni ó máa ń gbé ní ilẹ̀ Mọngolíà tí o kún fún koríko, lára wọn ni ẹṣin, ẹrinlá, ìbákasíẹ̀, àgùntàn, ewúrẹ́, àgbọ̀nrín àti ràkúnmí. Àwọn Darandaran máa ń mú oúnjẹ jáde láti ara ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ẹranko wọ̀nyìí.













# Oúnjẹ Ìfúnwàrà

Oúnjẹ láti ara ìfúnwàrà ṣe pàtàkì púpọ̀púpọ̀ nínú ìgbé-ayé ojoojúmọ́ àwọn ará ilẹ̀ Mongolíà. Ìwádìí àwọn onímọ̀ Aṣèwádìí-ohun-àdáyébá jẹ́ kí a mọ̀ pé àṣà yìí ti bẹ̀rẹ̀ láti nǹkan bíi, ó kéré tán, ẹgbẹ̀rún mẹ́ta lé ni ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta (3,500) ọdún sẹ́yìn.




## Àwọn Kòkòrò Àìfojúrí Inú Wàrà


Àwọn ogunlọ́gọ̀ kòkòrò àìfojúrí tó wà nínú wàrà - ní pàtàkì jùlọ kòkòrò bakitéríà àti Kòkòrò Amúwàràwú (yeast) - máa ń kó ipa pàtàkì nínú ìṣẹ̀dá oríṣiríṣi oúnjẹ láti ara wàrà, àwọn bíi yúgọ́ọ̀tì, òrí (bọ́tà) àti wàràǹkàsì, bákan náà ni àwọn oúnjẹ ilẹ̀ òkèèrè bíi (wàrà-gbígbẹ) ti àwọn ará ilẹ̀ Mongolíà aaruul àti (wàrà-ẹṣin) tí a ń pè ní Yíáráàgì airag.



# Àwọn Àìsàn Àdáyébá

Àwọn egungun, eyín, àti ìdọ̀tí eyín máa ń ṣe ìpamọ́ àwọn ìmọ̀ tó ṣe pàtàkì nípa ètò ìlera àwọn ènìyàn àtijọ́. Fún àpẹẹrẹ, abùdá àjogúnbá (DNA) àti èròjà amáradàgbà, èyí tó máa ń sá pamọ́ sí abẹ́ eyín máa ń ran àwọn onímọ̀ sáyẹ́ǹsì lọ́wọ́ láti ní òye ìtàn nípa àìsàn èrìgì àti bí eyín ṣe máa ń jẹrà.






## Omne Bonum


Omne Bonum jẹ́ ìwé ìmọ̀-ọ̀fẹ́ (ẹkisaikilopẹ́día) tí a gbé jáde ní ọ̀rúndún kẹrìnlá (14th century) tí ó wà ní yàrá ìyáwèé-kàwé ti ilẹ̀ Aláwọ̀ funfun Bírítéènì, ìwé ìmọ̀-ọ̀fẹ́ yìí ń sọ nípa ìgbé-ayé àwọn ara ilẹ̀ Yúróòpù àtijọ́. O níí ṣe pẹ̀lú àkọsílẹ̀ ìtọ́jú eyín àti ìtọjú ara nípa lílo oògùn òyìnbó, èyí tí ó le ràn wá lọ́wọ́ láti sọ nípa ètò ìlera àti àìsàn ìgbà àtijọ́.






# Àìsàn Ikọ́-Fée Àti Ààrùn Ẹ̀tẹ̀

Àìsàn ikọ́-fée àti ààrùn ẹ̀tẹ̀ máa ń wáyé nípa iṣẹ́ àwọn kòkòrò àìfojúrí bakitéríà: kòkòrò àìsàn ikọ́-fée *Mycobacterium tuberculosis* àti kòkòrò ààrùn ẹ̀tẹ̀ *Mycobacterium leprae*. Àwọn méjéèjì ni ó le ṣe àkóbá fún egungun, ìtọpasẹ̀ wọn lára àbùdá àjogúnbá (DNA) nínú àwọn egungun ènìyan àtijọ́ máa ń ran àwọn onímọ̀ sáyẹ́nsì lọ́wọ́ láti ṣàwárí ìtàn/ìmọ̀ nípa àwọn àìsàn ìgbà àtijọ́.





Mycobacterium leprae




# Cocoliztli

Àjàkálẹ̀-Àrùn kan tí a kò le ṣàfihàn- orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ cocoliztli láti ọwọ́ Aṣítẹ́kì ni ilẹ̀ Mẹ̀síkò. Àrùn yìí pa ìdá ọgọ́ta sí ìdá ààdọ́rùnún (60% - 90%) nínú iye àwọn ènìyàn ilẹ̀ Mẹ̀síkò láàrin Ọdún 1545 sí 1550 lẹ́yìn ikú olúwa wa (AD 1545 & 1550). Láìpẹ́ yìí a ṣàwárí àbùdá àjogúnbá (DNA) láti ara kòkòrò àrùn ibà jẹ̀fun-jẹ̀dọ̀ tí a mọ̀ sí *Salmonella enterica* Paratyphi C nínú eyín àwọn ènìyàn tó ní àrùn náà rí.






Salmonella enterica



### Dr. Schnabel

Oníṣègùn Òyìnbó tí ó ń tọ́jú aláìsàn náà ní ọ̀rúndún kẹtàdínlógún (17th century) máa ń wọ àwọn àgọ̀ tó dàbí ẹyẹ láti dáabò bo ara rẹ̀ kúrò lọ́wọ́ "afẹ́fẹ́ burúkú."





### Codex en Cruz


Àwòrán ènìyàn Aṣítẹ́kì yìí ti wà láti ọdún 1550, ó sì ń ṣàfihàn àwọn àmì àìsàn kókólísílì (cocoliztli): ibà, ifọ̀n-ooru àti dída ẹ̀jẹ̀ lọ́pọ̀lọpọ̀.

# Ààrùn Eku (Plague)

Kòkòrò àìfojúri bakitẹriọmù tí ó máa ń ràn *Yersinia pestis* láti ara kòkòrò tí ó ń gbé lára èkúté ni ó máa ń fa àjàkálẹ̀-àrùn Plague. Ẹnikẹ́ni tí kòkòrò yìí báti gé jẹ ni ó máa ní àrùn àwọ́kú (bubóníkì). Ààrùn yìí ni okùnfà Ikú Àwọ́kú (Black Death) (ní ọdún 1346 sí ọdún 1353 lẹ́yìn ikú Olúwa wa) (AD 1346 - 1353), èyí tí ó pa ìdajì àwọn ènìyàn ilẹ̀ Yúróòpù.








### Helicobacter pylori

Ó máa ń gbé inú ikùn ènìyàn, ó sì le fa àìsàn ọgbẹ́-inú àti oríṣì àwọn àìsàn jẹjẹrẹ kan




### Bifidobacterium

O máa ń ran ọmọ tuntun lọ́wọ́ láti jẹ́ kí omi ọmú dà




### Faecalibacterium

Ó máa ń pèsè oúnjẹ fún ìfun




### Prevotella

Kòkòrò tó ń ṣe ìrànlọ́wọ́ fún ìlànà ẹ̀dà oúnjẹ ajẹmọ́-ewéko




### Treponema

Kòkòrò yìí máa ń ṣe àtúpalẹ̀ èròjà ewéko àti fónrán inú oúnjẹ



# Máíkíróbíómù Àtìradiran (Àkójọpọ̀ Kòkòro Àgọ́-Ara)

**Ẹgbẹẹgbẹ̀rún lọ́nà ẹgbẹẹgbẹ̀rún** kòkòrò àìfojúrí bakitéríà ló ń gbé nínú àgọ́ ara rẹ, àpapọ̀ wọn ni a sì ń pè ní Máíkíróbíómù. Kòkòrò àìfojúrí bakitéríà tó wà nínú ìfun rẹ ni ó máa ń ràn ìlànà dídà oúnjẹ rẹ lọ́wọ́, ó sì máa ń fi àgbára kún àwọn èròjà tí ó máa ń bá àìsàn jà nínú àgọ́-ara (ètò àjẹsára) rẹ. Kòkòrò àìfojúrí bakitéríà tó wà nínú awọ ara rẹ ni ó máa ń jẹ́ kí ara rẹ wà ní mímọ́, kòkòrò àìfojúrí bakitéríà tó sì wà nínú àyíká ẹnu rẹ ni ó máa ń dáàbò bò ọ́ kúrò lọ́wọ́ àìsàn.



## Ǹjẹ́ o mọ̀ pé?

Àwọn Onímọ̀ sáyẹ́nsì máa ń ṣe ìwádìí lórí ìdọ̀tí eyín àti igbẹ àwọn ènìyàn àtijọ́ kí wọn baà le ṣe àlàyé kíkún nípa Máíkíróbíómù Àtìradiran àti láti ní òye ìjìnlẹ̀ nípa okùnfà àwọn àìsàn.



### Porphyromonas

# Àwọn Àgbẹ̀ Àtijọ́


Àwọn Adẹgbó ní a tún mọ̀ sí ọdẹ-aṣàtìpó tí wọn máa ń jẹ oúnjẹ àti ẹran tí a mú láti inú ẹgàn, ìsọwọ́jẹun wọn sì máà ń ní ṣe pẹ̀lú ìgbà àti àkókó.

Kí ó to di pé ìmọ̀ ètò-ọ̀gbìn dé ní nǹkan bí ẹgbẹ̀rún mẹ́wàá ọdún sẹ́yìn, gbogbo eniyàn lórí ilẹ̀ ayé ni wọ́n jẹ Adẹgbó.

Lóde-òní, àwọn Adẹgbó ní oríṣiríṣi kòkòrò àìfojúrí Máíkírobíòmù nínú ikùn wọn ju àwọn èniyàn tí ó wà ní àwọn àwùjọ aṣàmúlò ìmọ̀-ẹ̀rọ lọ.



Àwòrán Obìnrin Hádísà àti ọmọ rẹ, Tàǹsáníà



Àwòrán Obìnrin ará Amẹ́ríkà, ní orílẹ̀-èdè USA


# Àwùjọ Àṣàmúlò Ìmọ̀ Ẹ̀rọ

Àwùjọ aṣàmúlò ìmọ̀-ẹ̀rọ fún ìpèṣè oúnjẹ máa ń sábà jẹ àwọn oúnjẹ ajẹmọ́-étò-ọ̀gbìn, bákan náà ni ìpèṣè oúnjẹ ti wá di iṣẹ́ pàtàkì tí àwọn èniyàn àti ilé-iṣẹ́ péréte ń ṣe láwùjọ.

Ìsàmúlò ìmọ̀-ẹ̀rọ, ìdáàbòbò, àti ìkópamọ́ ni àwọn ohun tó ṣe pàtàkì jù fún ètò ìfimọ̀-ẹ̀rọ-pèṣè-oúnjẹ, àwọn oúnjẹ ìgbàlódé yìí sì máa ń rin ìrìn àjò lọ sí ọ̀nà jínjìn kí wọ́n tó di jíjẹ.


Àwọn èniyàn ti ó ń gbé àwùjọ aṣàmúlò ìmọ̀-ẹ̀rọ lóde òní kò ní ọ̀pọ̀ oríṣiríṣi èròjà abáìsànjà máíkirobíòmù nínú ikùn wọn, èyí sì lè jẹ́ kí wọ́n wà nínú ewu kíkó àwọn àrùn tí ó lè ba àgọ́ ara wọn jẹ́.

















# Ìrìnkèrindò Nínú

# Ìmọ̀ Sáyẹ́nsì Ìṣèwádìí-Ohun-Àdáyébá

## Ìwé Akọ́niláwọ̀

Kọ́ nípa bí àwọn Onímọ̀ nípa ìwádìí-ohun-àdáyébá àti onímọ̀ sáyẹ́nsì ṣe máa ń ṣiṣẹ́ papọ̀ láti wá ìdáhùn sí àwọn ìbéèrè nípa àwọn ẹ̀dá àtijọ́! Darapọ̀ mọ́ wa bí a ṣe ń ṣàlàyé nípa **ẹni tí a jẹ́** àti **ohun tí a ń ṣe ìwádìí lé lórí**, láti **orírun ènìyàn** títí dé **àwọn àrùn àtijọ́**. Kọ́ nípa **ìgbòkegbodò ènìyàn àtijọ** àti **ṣíṣàwárí ọjọ́ orí ohun àtijọ́**. Wo bí àwọn onímọ̀ sáyẹ́nsì ṣe ṣàwárí àwọn **oúnjẹ àtijọ́** láti ara àwọn èérún ewéko àìfojúri tó ṣẹ́kù. Àwọn ẹ̀rí **ohun ọ̀sìn ìbílẹ̀** tí a wú láti inú ilẹ̀, àti ìmọ̀ sáyẹ́nsì tó wà nínú ìpèsè àwọn **oúnjẹ ìfúnwàrà**. Ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn **àìsàn** àti **àjàkálẹ̀-àrun àtijọ́**, kí o sì ṣàwárí àwọn **àkójọpọ̀ kòkòrò àìfojúrí Máíkíróbíòmù nínú ìrandíran ènìyàn.**

A tẹ ìwé yìí jáde láti Ilé-Ẹ̀kọ́ Max Planck fun ìmọ̀ Sáyẹ́nsì ìtàn Ẹdá.

A túmọ̀ Iṣẹ́ yìí sí èdè Yorùbá láti ọwọ́: Oníṣègùn Òyìnbó Ìféolúwa Òjélabí. Olùkàwé: Ìyáàfin Rachael F. Àkàndé.

